# ELETI ỌFẸ

'A-NJU-WỌN KO ṢE WI LẸJỌ'

VLO XIV NO 895 LAGOS SATURDAY NOV, 16 — NOVEMBER 22 1963 KỌBỌ MEJI (2D)


# Sangba Fo! Awon Olosa Ko Sosi Pataki Nilu Abeokuta: Awon Alufa Ko R'aso Wo

ABẸOKUTA — Awọn akọrin Ṣọṣi mẹrin pataki ni ilu Ẹgba ni nwọn ko ni ri aṣọ akọrin wọ pẹlu awọn alufa ijọ wọn ni owurọ ọla ti nwọn ba lọ jọsin nitoripe gbogbo aṣọ wọn ti nwọn ko sinu Ṣọṣi ni awọn Ọlọṣa ti ko lọ bamu-bamu laida ọkan si. Awọn Ṣọṣi mẹrin na ni St, Peter's (CMS) Ake, St Paul's (Aguda) Itẹssi, Methodist Ọgbẹ ati Ṣọṣi Afrika ni Idi-Apẹ.

Osirohin wa ni [oibiti awọn ọlọpa ni awọn Ọlọṣa na ti wa si ilu Ẹgba ko ye awọn rara nitoripe nwọn so ipanpa ni, loru ọjọ kanna ni nwọn wọ gbogbo awọn Ṣọṣi na ti nwọn ji agogo ara ogiri, aṣọ awọn alufa ati aṣọ awọn akọrin gbe pẹlu aṣọ ti nwọn ntẹ si iwaju pẹpẹ awọn alufa.

Nwọn ni awọn moto-akẹru ni awọn ọlọṣa na gbe wa fi ko awọn ẹru na. Awọn ọlọpa si wa lẹnu wipe nwọn nwa awọn ọlọṣa na lọ si ọna ilu awọn Egun ni Dahomey.

## Sunbo Jibowu Jalaisi

EKO—Ẹnikan ninu awọn mẹtadinlogun ti adajọ George Showẹmimọ da ẹjọ fun pẹlu Awolọwọ ninu oṣu September wipe o jẹbi nkan ọṣẹ ti nwọn ko wọlu lati bi Ijọba ṣubu ni a gbọ wipe o jalaisi si ile awọn alamodi ni ana, Ọgbẹni na ni Suembọ Jibowu.

Irohin ti a gbọ nipa iku rọ ni wipe ni ọsan Ijeje ni o sọ fun awọn ti nwọn ntọju rẹ lọgba ni Ikoyi wipe ara on ko da, nwọn si mu u wa si ile iwosan fun itọju. Nigbati awọn dọkita yẹẹ v o, nwọn ri wipe amodi rẹ na gba nkan ti nwọn ni lati lo abẹ fun. Nwọn lọ abẹ fun un, ṣugbọn Sunmbọ ju ẹgẹ nu loru ijẹta.

Ẹnikan ti a tun gbọ wipe ara rọ ko da ninu awọn oṣelu ti nwọn wa lẹwọn na ni Sam Onitiri. A gbọ wipe nwọn ti ru on na lọ si ile iwosan ni Suru-Lere.

### Oko Iyawo Da?

## Adajo Ni K'Iyawo Olowogbowo Re

EKO— Gbogbo awọn enia ti o wa si kotu awọn ọlọpa ni nwọn bu sẹrin nigbati ọmọge kan ti nwọn npe orukọ rẹ ni Olufẹmi Sule tu ọrọ ikọkọ ti on pẹlu 'onitiju' rẹ Ọgbẹni Adebisi MacGregor ti o mba awọn Oyinbo German ọlọkọ ofurufu ṣiṣẹ ti o fi de ibi wipe ti nhu si gbangba, ọmọge Sule na fi nya MacGregor ni adọjọ pọnun (£150) ninu owo ti o ti tu pamọ lati fi ṣe ire fun ara rẹ.

Ṣugbọn ni ọsẹ ti o kọja yi ni adajọ Akintoye Ṣowẹmimọ ti nwọn ... ẹjọ na niwaju rẹ gbegi le wipe ki MacGregor lọ san owo ọmọge na fun pẹlu owo irin ẹsẹ; gbogbo owo ti adajọ ni ki MacGregor san fun obinrin na pẹlu owo irin ẹsẹ jẹ pọnun mejidinladọsan (£168).

A gbọ wipe MacGregor ti ọmọge Sule pe lẹjọ fi igba kan wa pọ, nwọn si ngbe ara wọn kiri bi tọkọ taya oju ọ n a. Nigbati ede aiyede wọ ... won, ṣugbọn ko to to bẹ iyawo oju-ọna yi ti ya MacGregor lowo lati fi ṣe aṣeyẹ fun Oyinbo ọga rẹ rẹ nibi iṣẹ.

MacGregor ni on ko fi igba kan yawo lọwọ ọmọge na, o ni on funrarẹ ni lẹbun kan nigbati on fẹ ṣe ọjẹbi, o ni ọmọbinrin na si tun fun on ni ọgọta pọnun ṣarayi nigbati on fọ ra nkan ọṣẹ sile ti on ṣẹṣẹ ko lọ.

Ọmọge Sule ti o pe "onitiju" rẹ lẹjọ yi ni Mac Gregor ni o ni oyun ti o

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

## Ọkunrin Kan Ku Soko Ole L'Eko

EKO—Ọpọlọpọ enia ni nwọn nsọnu l'EKO ti a wa yi, ti awọn ara wọn ma nsọ wipe boya aganna tabi awọn enia buruku ni o ji wọn gbe lọ, ti o si jẹ wipe nibi iṣẹ buruku ti nwọn lọ ṣe loru-ganjọ ni nwọn ku si.

Iroh... kan ti a gbọ ni... ...rin kan (ti a ko pa ọmọkun... ti a gbọ wipe mọ orukọ rẹ) ... won o ku sibi ti o ti ... ṣẹwọde ole lẹ ni o jẹki ... rọ yi.

Ni Oke-Suna nibiti awọn Oyinbo kọle-kọle kan ti nwọn npe orukọ wọn ni Cappa D'Alberto gbe ko ẹru irin ikọle wọn si, ni a gbọ wipe awọn ọlọṣa yi gbe ọkọ oju-omi lọ lati ji awọn irin ikọ'e gbe nibẹ.

(Wo yoku loju ewe kẹjọ

# Elewon Kan Fodun Meta Sa Kiri

IBADAN — Arufin kan Lawal Ayọdele ti awọn ọlọpa ti nfi ọdun mẹta gbako wakiri ni a gbọ wipe ọwọ awọn ọlọpa tẹ nibiti o gbe ti nṣe ọmọjaiyejaiye ni adugbo kan ni Ibadan, nwọn si mu lọ si ọgba ẹwọn agodi wipe ki o lọ bẹrẹ ẹwọn ti o nsa fun na.

Adajọ Kotu awọn ọlọpa ni ni ọdun 1958 nigbati awọn kan bẹresi ta adamọdi iwe aṣẹ-mọtọ kakiri ni nwọn mu arufin na lara awọn ti nwọn nta iwe madaru na. Ẹwọn ọdun mẹta ni adajọ Morgan ju arufin na si ni Kotu awọn ọlọpa.

Lẹhin eyi arufin na gbe ejọ rẹ lọ si kotu ko-tẹmi lọrun; ki nwọn to gbọ ẹjọ rẹ ninu kotu na, nwọn ni ki o wa ẹni duro fun un Lọjọ keji ti nwọn ti duro fun un ni ọdaran na ti sa kuro nilu ati baba onidurọ rẹ, awọn ọlọpa fi ọdun mẹta gbako wa a, ki awọn to ṣẹṣẹ ri ti o wọlu lẹhinti nwọn ti tun dejọ rẹ ni kotu ko-tẹ-mi lọrun

Irohin ti a gbọ nipe arufin na ṣebi bi on ba salọ, ti ọdun ẹwọn on ba ti kọja, awọn ọlọpa ko le mu on mọ.

Irọ ni eyi, igbakugba ni awọn ọlọpa le mu arufin ti o salọ fun ẹsun rẹ.

# Dokita Azikiwe Gbayi Ni Ilorin

ILỌRIN–Dokita Nnamidi Azikiwe tiṣe balẹ Ijọba ilẹ Nigeria gbayi o tun gba ẹyẹ lọjọ ti ọkọ rẹ gunlẹ ni Ilọrin fun abẹwo ọjọ diẹ ti o lọ ṣe ni agbegbe ilu na.

Lehin ti awọn ara ilu Ilọrin ti gba Ọlọla Azikiwe tọwọ tẹsẹ tan ni o wa gba ilu ti nwon npe ni Bacita, nibiti nwọn gbe ti nṣe ṣuga lọ lati lọ wo ibẹ. Ọba Ilọrin, Alhaji Sulu Gambari pẹlu awọn ẹmẹwa rẹ si tẹlẹ e lẹhin

Ki nwọn to wọ ilu na ni awọn oloye agbegbe ibẹ, awọn bi Malam Umaru Oke-ọdẹ, Olori Shonga, Malam Alahsan ati Alhaji Sule Ndakpoto ti wa pade wọn lọna, ti nwọn si tẹlẹ Ọlọla Azikiwe ati ọba Ilọrin lẹhin wọ ile iṣe ṣuga na.

Oyinbo ọga ibi iṣẹ na ti orukọ rẹ njẹ W. A. Fraser ni o fi gbogbo nkan eto ti nwọn nṣe lori ẹrọ iṣẹ ṣuga na han wọn patapata



DR. NNAMDI AZIKIWE (Balẹ Apapọ ilu Nigeria)

# Eleti—Ofe D'araba

Nigerian Women:

# Social Welfare Leaders in Britain

LONDON Four social welfare leaders, all of the Nigerian Federation of Business and Professional Women, are now in Great Britain as guests of the British Governmen.

They are Mrs. J. Awokoya, Headmistress of the Domestic Science Centre, Girls Modern Academy, Lagos; Mrs. A L D Ajayu, President of the Business and Professional Women's Society in Enugu, Mrs. A T Banjo of Lagos, a housewife and voluntary workea for the Y W C A and the Nigerian Leprosy Relief Assocation: and Mrs. E.O. Priddy, Headmistress of the Anglican Girls' Secondary Modern School Ibadan.

They begin their tour by visits in London to the headquaters of the British Red Cross Society the Y W C A and National Council for Women. They will have discussions at the Commonwealth Relations Office and the Ministry of Education, see examples of nursery and comprehensive schools run by the London County Council and lunch at the Women's Press Club.

On leaving London they will tour Wales and south west England and later travel to Scotland for sightseeing and to meet teachers and voluntary workers from women's organisations. The four ladies will return to Nigeria on '11th December,

Olofintoto Wo:

# Ile Iwosan Awon Egbe Onisegun

Njẹ lati igbati a ti gba ominira alagbatan ẹnyin ọkawe mi ṣe akiyesi nkan orişirişi, awọn nkan idẹra ti nwọn ngbe wọ ilẹ yi? Bi ẹ ko ba ṣe akiyesi wọn ma fi ọkan ti mo ri, ti mo si ṣe ofintoto rẹ fun yin ni ọsẹ yi— iyẹn ni ILE IWOSAN AWỌN ẸGBẸ ONIṢEGUN ti nwọn ṣẹṣẹ şi si ẹja ita Faji l'Eko ni opopo ti nwọn npe ni Willoughby lẹ i ile ti Ologbe Alhaji Ọlọrunnimbẹ ti nta bọtini ati owu maşini latijọ.

## Oruko Nla

Ki nto ma sọ awọn nkan ti mo ri ninu ile iwosan awọn onişegun ibilẹ na fun yin, mo fẹ ki ẹ mọ orukọ ẹgbẹ wọn na ti nwọn da silẹ ni ọdun 1947— odun mẹrindilogun sẹhin, Orukọ wọn na njẹ Nigerian Association of Medical Harbalists; itumọ ti emi OLOFINTOTO le fun orukọ wọn na ni awọn Ẹgbẹ Ti nwọn nfi ewe ilẹ wa şe iwosan. Awọn ẹgbẹ na ni nwọn şe eto ẹgbẹ iwadi ọna ti a le gba fi ewe ilẹ wa şe iwosan orişirişi awọn arun ti nwọn mba ọkunrin ati obinrin ja.

Oru'kọ Nigeria Harbal Reserch and Healing Centre ni nwọn sọ ẹgbẹ iwadi egbogi na, nwọn si ni ẹka kakiri gbogbo ilẹ Nigeria Nwọn wa ni Ibadan ni Ipinlẹ Iwọ Orun, Kaduna ni Ipinlẹ Ariwa ati ni ipinlẹ tuntun ti nwọn ṣẹṣẹ dasilẹ ni Benin City.

## Ero

Awọn ẹgbẹ yi ni awọn ri wipe o yẹ ki awa ọmọ ile Nigeria paapa ti Ọlọrun fi ewe orişirişi daradara fun si lo wọn fun ire ilu wa ni ọpọlọpọ.

## Alafia Ara

Ni ọjọ ti mo de ile iwosan aọwn onişegun na mọ ri orişirişi egbogi ti nwọn fi ewe ilẹ wa şe ni ọna ara fun alafia awọn ti nwọn nfẹ iwosan— gbogbo awọn egbogi na ni nwọn lẹ iwe mọ lara patapata.

Dokita Z. O Salimon pẹlu awọn ẹlẹgbẹ rẹ fi ọna ti nwọn ngba lo erọ lati fi şe iwadi arun lara enia han mi. Mo gbọ wipe ko si iru amodi arun ti nwọn ko lo wo san ninu ile iwosan na ni ọpọlọpọ awọn enia lọkunrin ati ti nlọ sibẹ fun iwosan; owo ti nwọn si ngba nibẹ ko ju pọ ju, nwọn si şe eto bi enia şe le ma san owo diẹdiẹ loşoşu.

## Arun Ara Obinrin

Arun ki oyun odun kan dabi oşu mẹta tabi ki obinrin ma ri ẹjẹ ninu oyun loşoşu, arun ni o fa a. Bi obinrin ko ba ri nkan oşu, ti ko si ni oyun tabi ki inu obinrin tobi lasiko ti ko loyun; ki ẹda ma yọ obinrin lẹnu tabi ki nkan ma yika nu obinrin. Arun afişe tabi kiko lara enia.

## Ara Okunrin

Bi nkan ọmọkunrin ba şan, ti o domi, ẹhin didun, jẹdjẹdi igbẹ ọrin, arun kunsinu, gunsode, ipakeatọsi ati ara gbigbona, egbogi wa fun iwosan iru awọnarun bẹ.

Obinrin kan ti mo ba pade nibẹ ni abẹnu ti o ti dun on ti nfuyẹ diẹdiẹ, on si nri alafia lọna ti on ko ro.

(Wo yoku loju ewe kẹfa)



Eleyi kise angeli ti Itolo l'Eko rara, ni owon ile ijosin kan ni ilu Oyinbo ni nwon gbe angeli ti o fe fi ida gun esu yi si.

E ma ka

Iwe Irohin Eleti-Ofe

Losose

O kun fun irohin aladun.

# ELETI-OFE

( ANJU WỌN KOSE WI EBỌ )

EDITORIAL OFFICE & WORKS 38, Kosọkọ Street, Lagos, P. O. Box 467
CABLE & TELEGRAMS "ELETI-OFẸ" LAGOS Phone 23370

VOL. XIV. NO 515 SATURDAY NOV. 16 - NOV 22, 1963


ỌRỌ OLOTU

## Ile Iwosan Ibile Wa

Awọn Yoruba ni awọn pa owe wipe ọmọ ale enia ni o ma nfi ọwọ osi juwe ile baba rẹ. Itumọ ọrọ yi ni wipe enikeni ti nkan ti nwọn ba bi i mọ ko ba wu a jẹ wipe oluwa rẹ kiṣe ọmọ ọkọ ti iya rẹ sọ wipe on bi ọmọ na fun.

Ọrọ ti a fẹ fi gba ẹnyin ara wa ni iyanju lọsẹ yi ni ti ile iwosan ibilẹ ti awọn gbogbo oniṣegun si si Eko fun anfani awọn ara ilu wa. A gbọ wipe awọn ẹgbẹ ti nwọn npe Nigerian Association of Medical Herbalist ti nwọn da ile iwadi iwosan e'ẹkunrẹrẹ ti nwọn sọ ni HERBAL RESEARCH and HEALING CENTRE silẹ ni iwe-ẹri iwosan ni ọdọ awọn alakoso eto egbogi lọdọ Ijọba Iwe-ẹri wipe nwọn ko ni fun ara ilu ni majele jẹ.

### Dara Pupo

Iwe-ẹri wipe egbogi alanfani ni nwọn yio ma ṣe ninu ile iwosan wọn ati pe ewe ilẹ wa pelu gbogbo itakun awọn igi ilẹ wa na ti o kun fun awọn oro imularada ni nwọn yio ma fi ṣe iwadi, ti nwọn yio si ma lo fun gbogbo ire wa. Eleyi dara pupọ, ṣugbọn nkankan ni o ba wa jẹ nilẹ yi.

### Sugbon

Kini nkan na? A ki fẹ lati ran ara wa lọwọ lori nkan ti o le mu ire wa fun orilẹ-ede wa. Nkan ti o bi ti ilẹ ajoji wa le ya wa lara pupọ ju.

Tani ko mọ wipe owo ni koko ninu aiye ti a wa yi? Bi a ba tẹti silẹ fun irohin agbaiye kakiri a o ma gbọ wipe alanu ilu Ijọba Gẹsi kan tabi ni ilu Amẹrika fun awọn akẹkọ kan lowo gọbọyi wipe ki nwọn ri nkan ṣe fun iwadi egbogi fun anfani awọn araiye.

Eleyi ko si ninu ero ti wa, a fi bi o ba ba a ki a pa a, bi o ko si ba ba a ki o bun lẹsẹ ti a mba kiri loju jumọ. Iru ile iwosan ibilẹ ti nwọn da silẹ ni o yẹ ki awọn ti nwọn ba lowo nina wa parapọ ki wọn ṣe iranlọwọ fun awọn ẹjọgbọn ti nwọn nko ọgbọn jẹ lori bi a ti le lo awọn ewe ilẹ wa fun ire awọn ti nwọn mbọ lẹhin wa.

### Ijoba Nko?

A gbọ ti awọn ara wa anikanjọpọn, ti Ijọba wa paapa nkọ? Ṣe awọn olotu ile iṣẹ iwosan ilẹ wa fẹ sọ fun wa wipe ko si nkan rere kan ti a le ri lọdọ awọn oniṣegun ibilẹ wa ni? Bi awọn kan tilẹ sọ bẹ awa oniwe irohin Eleti-Ọfẹ le ko eyi si wọn lapo nitoripe ki awọn Oyinbo ajeji to ko ogun wọn wọ ilu yi ni awọn baba wa ti nlo ewe ilẹ wa fun iwosan awọn ọmọ wọn, nkan ti o ku ninu eto egbogi wa na ni akọsilẹ ti a ko ni tobẹ.

(Wo iyoku lapa keji)

## Iwe Si Olotu

ỌRỌ OLOTU

### Dan Nwon Wo

O da wa loju wipe bi awọn oniṣegun ibilẹ wa yi ba ri iranwọ owo tabi nkan bẹ gba lowọ Ijọba wa awọn na le ran enia lọ si ilu okere bi ilu Gẹsi (England) Amẹrika, India Russia ati Germany lati lọ ṣe iwadi lori awọn ewe ilẹ wa ti a le lo ni oriṣiriṣi fun arun ode isisiyi.

A gbọ wipe ko si arun ti awọn ẹgbẹ oniṣegun ibilẹ wa ko le wo san. Ọrọ re o, ẹnyin ara ilu wa, Ọlọrun ma jẹki a ri arun ti ko gbogun ṣugbọn bi ẹ ba ni alamodi kan ti o nfẹ iwosan ẹ gbe lọ sọdọ awọn ara wa yi. Awọn dokita oloyinbo paapa le fi alamodi ranṣẹ sọdọ wọn, ko si itiju nibẹ. Awọn babalawo ni Ọrunmila ni ajọwo nkan ti a ba jọwo gigun ni i gun.

Ọrọ re o

## Iya "Fadaka" Se Aseye Ojobi



EKO—Gbogbo awọn gbajumọ Eko ni o pesẹ si ibi aṣeyẹ ọjọbi ti awọn ọmọ Iya-afin Amọta Alake (aya Ologbe Lamidi Thompson) ni Idita se fun adọrin ọdun ti o da ninu ọsẹ yi. Isin idupẹ ti nwọn ṣe fun iya na ni Mọsalasi Idita lojọ Jimọ dun pupọ.

A ki nwọn ọmọ iya na, awọn bi Ọgbẹni M. A. Thompson (ọga ile iṣẹ Barclay Bank), Taju Thompson (ọga ile iṣẹ Eleti—Ọfẹ) ati Nusiratu Ayinkẹ Thompson awọn ọmọ ọmọ rẹ, nwọn ku inawo.

Awa Eleti-Ọfẹ ki iya "Fadaka wipe a ṣe yi ṣe ẹmu!

# Nihin Lohun Ati Nibi Gbogbo

**Lati Owo Ayiluka**

## Adele Oba

Ẹnyin ọkawe mi, ẹ jọwọ mo fẹ bẹ yin ni ẹbẹ kan, ẹbẹ na ni wipe ki ẹ ba mi ba Ọba Adeniji Adele Keji ni Isalẹ Eko yọ fun ajọyọ ti ADỌRIN ọdun ti o da ni ijẹta OJỌ'RU. Adọrin Ọdun kiṣe yẹyẹ ẹnyin ara mi! Bi ẹnia ba di ọmọ ogoji ẹdun ti a a ti bi i saiye, o ni lati mọ iwọn ara rẹ, ko gbọdọ si nidi yẹyẹ mọ rara. Bi o ba ti npa irọ pupọ ri, o ni lati din irọ na ku, o ko si gbọdọ fi ibi iṣẹ rẹ ti o ti nri onjẹ ojọ rẹ jẹ ṣere rara. Iyẹn bẹ nipa ọmọ ogoji ọdun.

## Ori Eja

Mo niran ọdun ti emi Ayiluka pappa di ọmọ ogoji ọdun, awọn ọrẹ mi ni emi na di bale ile niyẹn; bi awọn ara abule wa ba fẹ pari ija pẹlu awọn ara abule keji nwọn a si ma pe mi sibẹ. Oriṣiriṣi eto igbimọ ni nwọn si nyan mi si. Gbogbo nkan ti o ti jọ mi loju nigba mo wa lọdọ wa di yẹpẹyẹrẹ loju mi ṣugbọn nko jẹ fi enia ṣe yẹyẹ, Mo bẹru agba pupọ.

## Dori Malu

ADELE ỌLỌGBỌN DORI ẸJA MU ni a ti ngbọ ọrọ na wa di ọrọ ADELE ọmọ BURAIMO gba ori malu mu ṣinṣinṣin. Malu ti Ọlọla Tafawa Balewa, olotu ilẹ Nigeria fi ta Ọba Adele lọrẹ fun ajọdun ọjọbi rẹ ti o ṣe na ko si abawọn kan lara rẹ rara. Boya Ọlọla Tafawa Balewa fi eyi powe ni, ko ye mi si rara sugbọn ẹniti ọjọ ori rẹ ba ti di adọrin ọdun di BABA OLOGBONI (ti o ba fẹ ọkunrin) bi o ba jẹ obin rin o ti di IYA ARUGBO, aṣẹ si mbẹ lẹnu rẹ, nitorina iwọ paapa ni lati ni ọnu pupọ ki o si ma huwa agba nitori pe ọjọ alukiyan at nsnọ mọ ile. Eeyi lo mu mi sọ wipe adọrin ọdun kiṣe yẹyẹ, ọdun arugbo ni.



ỌBA ADELE KEJI

## IYA "FADAKA"

Ẹnikeji pataki ti o tun ṣe ajẹyẹ adọrin ọdun ti nwọn ti bi i saiye lọsẹ yi ni Iya afin wa, Amọta Alakẹ (aya Ologbe Launid Thomson) ẹniti awọn ara Idita npe ni Iya Fadaka l'Eko. Awọn ọmọ ati ọmọ ọmọ rẹ ṣe aṣeyẹ fun un. Mo ki ya wa na wipe o ku ajọdun, ṣugbọn ki awọn ọmọ rẹ ma gbagbe nkan alejo temi Ayiluka. Bi nko ri omi-toro malu Ọba Adele jẹ, o yẹ ki nri ti agbo iya Fadaka fi jẹ amala.

## E KU ODUN

Boya ti mo ba sọ fun awọn ọmọ iya na, awọn bi Murano, Taju, ati Nusi pẹlu awọn ọmọ ọmọ, awọn bi Isiaka, Tunde ati Adukẹ awọn le tete gbe awo ọka te mi wa fun mi. Ọrẹ mi, awọn enia pọ pupọ ju lori malu Ọba Adele, awọn Oloye bi Ajirọba, Aṣiwaju, Balogun Ọtun Balogun ati Osi Balogun wa nibẹ, a ko ti ka awọn Oloye Oluwa, Eletu Iwaṣẹ, Eletu Odibo, Onisemọ Ọjọra, Ọlọtọ, Ọjọn Saba ati Bajulaiye, bẹ awọn ni agba Oloye ti nwọn ni lati gba ibi ti o dara lara malu na.

## Olopa Gberan

Ọlọla Tafawa Balewa ṣe pupọ nkan ti a ba ni ni a fi nta ni lọrẹ. Bi on na ti fi malu funfun ta Ọba lọrẹ yi bi o ba di akoko ti Ọlọla Tafawa Balewa na on na a fi ẹru obi gbanja funfun ti Shagamu ati obi Agege ta a lọrẹ pẹlu GORO IJỌ kiṣe gbanja - pade-agbako.

Ọrọ malu ti nwọn fun ọba Adele yi jẹki nniran awọn malu kan ọlọra ti Ọlọla Tafawa Balewa fun awọn ọlọpa Eko lori wahala wọn ti nwọn ṣe lori ẹjọ Awolọwọ ati lori ominira agbatan ti a ṣeṣe gba yi.

Ẹ ku inawe!

(Wo yoku loju ewe kẹjọ)

# O Digba o!



Aworan oke yi ni ti awon Jagunjgaun Ile Ajoji ti won mura Irin Ajo won.

# Ikede Egbe Olomo Tuntun

Arakunr n ati arabinrin ohun pataki to mu wa da ẹgbẹ yi silẹ ni ifẹ ilu wa Nigeria papa julọ fun ilọsiwaju gbogbo ọmọ ilẹ Yoruba nile ati ni ilu okere. Ọlọrun ti bukun awa ọmọ Yoruba pupọ yala nipa ọna iwe mimọ (Education) tabi ọna owo şişe (Trading) tabi ni ọna orişirişi miran ti ẹnn ko le ka tan.

Ki awọn oyinbo to wọ ilẹ wa ni awọn baba wa ti nwọ aşọ, ti wọn ti nda ina pẹlu lẹwu ọpẹ ati akọ okuta meji, ti wọn ti ngbe iyawo ti wọn si ni ọkọ (marriage). Gbogbo awọn ilaju ode asiko wọnyi ko şajeji fun awa ọmọ Yoruba rara tabi fun awọn baba wa.

Şugbọn ki lo nşẹlẹ lasiko yi, adiẹ funfun wa ko mọ ara rẹ lagba nibi ijẹkujẹ ati iwakiwa. K ẹni iwaju ma ba di ẹni ẹhin, lọjọ iwaju eyiti yio mu gbogbo wa kabamọ, lo mu awọn agbagba kan ronu wipe ki o to kọja pupọ ju ki a şe ra ni 'oşuşu' ọwọ ti ko ni şe şẹ.

Nitoripe 'ẹmọ nlọ afe nlọ' toto, o şe bi owe. Ẹlomiran le ma ro wipe 'şe gbogbo wọn ngun mọto ọmọ wọn nlọ silu oyinbo.' 'Njẹ iwọ le sọ pe ọmọ tiwọ papa ko le gun mọto lọla tabi di dokita tabi lọya.

Mọ daju pe awọn to şe mọto, to şe iwe ofin işẹ ọya to si şe iwe işẹ doktia ko jẹ igbadun rẹ gẹgẹbi awa iran asiko yi. Şugbọn orukọ wọn wa fun iranti irandiran, yala olowo ni o tabi talaka tabi bọrọ-aini, o yẹ ki iwọ papa jẹ ọkan ninu ẹgbẹ yi laisi idaduro, ti iwe yi ba tẹ ọ lọwọ.

Ya'a wa forukọ silẹ ki o si şişẹ tọkantọkan laiboju wo ẹhin ninu ẸGBẸ ỌLỌMỌ TUNTUN.

Kọwe si aşoju Ẹgbẹ yi No. 139 IGBOSERE ROAD, LAGOS


**• HINDU SANKARA'S •**
**Religious Art Jewelleries**



Perfumes, Charms, Mohammedan charms, Amulets, Vedic Prayers, Kawachas. Faithful Reproductions of Hindu Gods in the Jewelleries.

*Enclose 4/- British Postal Order by airmail for catalogues and literature.*

HINDU SANKARA, 431 Archway Road, London, N.6, England


Aroju-owo kişe ẹşọ-iyẹn ni ti arabinrin Oyinbo yi ti o nfin ikọrun olowo iyebiye kan ti o şẹşẹ tun ra fi han awọn ara adugbo rẹ. Awọn Oyinbo ki fi ilẹkẹ olowoiyebiye şere rara.

# Ile Iwosan Awon Egbe Onisegun

(O bẹ ẹ loju ewe kẹta)

## Awon Omode

Iya alabiyamọ kan ti oke-ilẹ nse ọmọ rẹ ni on dupẹ lọwọ Ọlọrun nitori ile egbogi ti nwọn fun on pati lo fun ọmọ na dara pupọ.

Gbogbo egbogi ti nwọn nlo ni ile iwosan na ni nwọn ti lo ngan ti nwọn ko fi ni dibajẹ si. Bi nwọn ba fun ọ ni agbo inu nibẹ wọ na a ri wipe agbo na nta sansan.

Ile Iwosan Eko yi nikan kọ ni nwọn ni, mo gbọ wipe nwọn tun ni ile iwosan miran ni ibomiran ti ẹka ẹgbẹ wọn wa. Irohin ko to afojuba ni ọrọ ile iwosan wọn na.



## Olopa Kan Wewon Nitori Arufin

EKO—Adajọ Kotu awọn Ọlọpa ju Ọlọpa kan ti orukọ rẹ njẹ Richard Emejulu si ẹwọn ọdun kan ati abọ nitoripe o jẹbi ẹsun ti awọn ọlọpa egbẹ rẹ fi sun wipe o jẹki arufin kan salọ mọ on lọwọ.

Gẹgẹbi ẹjọ ti awọn ọlọpa ro mọ ọkunrin yi lẹsẹ, nwọn ni Ijọba mba awọn mẹfa kan ti nwọn ji owo gọbọyi kan gbe rojọ lọwọ ni kotu ganran, nwọn si ko wọn sinu ile itimọle ninu iyara kan ni kotu na.

Lọjọ ti adajọ fẹ da ẹjọ wọn ni ọkan ninu awọn ọdaran na ti orukọ rẹ njẹ Benedict Iwunze fi ọgbọn ọwẹ salọ; nwọn ni ọlọpa yi ni o fi ẹhin pọn ti o fi ri ọna salọ.

Awọn ọlọpa ni awọn ko si ti ri arufin na mu doni.

### British Prime Miniter Says:

# All Talk And Thought Of War To End

LONDON – On his first appearance as Prime Minister at the Lord Mayor's Banquet in Guildhall London, last Monday night, Sir Alec Douglas-Home declared that Britain had the right, the duty and the authority to respond to the longing of the world's nations that she would exercise her full influence on the world stage. Her Foreign Secretary would have to conduct perhaps the biggest diplomatic operation of all time, said Sir Alec, because his aim was nothing less than to reverse the thinking and actions of men throughout the ages.

"He must take the message to 'the international councils that man must stop fighting wars and give up thinking of settling disputes by war," the Prime Minister said "Statesmen of the world c nnot use such phrases as 'OVER OUR DEAD BODIES,' because that means war."

All the difficulties, including Berlin, must be settled by negotiation, no matter how long these negotiations might last, because, said Sir Alec, 'There is no other way' The dictum that 'war is a continuation of diplomacy by other means" must not be heard again.

Sir Alec continued: "If war, which has been the traditional method by which we have settled our disputes, is to be ruled out of order now, certainly by the major powers and if the aggressive instincts are to give place to self-preservation, then Mr. Butler must go out into the world and tell the people to turn back in their tracks."

"Peace and security is our goal, and we passionately seek it, Sir Alec Said. "We know that war impoverishes us as a nation and xhausts our people."

"I believe we may be over the watershed of danger with the Soviet Union but if so it is because the the deterrent has deterred and above all because the Polaris submarine, as a second strike weapon, has convinced the Soviet Union that war is too dangerous."

Nuclear arm could not be wicked or too expensive commented Sir Alec, if the deterrent stopped war.

## British Troops Will Move From Kenya

NAIROBI— British troops at present stationed in Kenya will be withdrawn during the first year after the country's independence on December 12.

The timing has been agreed by the British and Kenya Governments and details of the phased troop movements have been announced from East Africa Command Headquarters, in Nairobi.

The 1st Battalion, the Gordon Highlanders, will be moved to Edinburgh in March. The 2nd Battalion, the Scots Guards, go to Pirbright later in the year and the last quarter of the year.

Units of the Royal Horse Artillery, the Royal Engineers and the Staffordshire Regiment will return to Britain. Head quarters of 24 Infantry Brigade Group, to which all troops in Kenya belong, are destined for Aden along with most of the Brigade's administrative units.

The future of the static workshop and depots in East Africa is "under active consideration with the Kenya Gorvernment," said the Nairobi statement.

### Boon For Salesman:

## African Workers Get More Pay In Rhodesia

N. RHODESIA—The National Union of Commercial and Industrial workers in Nothern Rhodesia have seccessfully concluded an agreement on wages and service conditions for African shop workers.

The new agreement provides a 40 per cent wage increase for employees earning not more than £25 per month, and increases ranging from 15 to 25 per cent for other categories. This implies that the lowest paid employes, formerly on £8 5/- will now receive £11 11/-. In the case of salesmen the increase is £9 5/- to £16 13/- The new rate for senior salemen is £20 5/- These new rates apply to towns on the rail line from Bencroft to Livingstone; shop employees in the rural areas will normally get two-thirds of the Town rates.

Paid leave entitlement is now 24 days a year instead of 21 and there is provision for overtime and for subsistence allowance of 22s 6d a night in the towns and 12s. in rural areas. There was no agreement on the unions' demand for an average rent allowance of £5 a month. The matter has been referred to the Minister of Laboar for ruling. The Minister has also been asked to work out on a national basis a provident fund scheme.

The new agreement puts employees into categories (including tailors, drivers, office workers, repairers of watches, shoes, bicycles and wireless sets, etc) for pay purposes.

## Majority Rule In Southern Rhodesia

LONDON

Majority rule giving protection for minorities will guide the British Government when they come to make decisions about the future of Southern Rodesia, said the British Prime Minister, Sir Alec Doglass-Home yesterday, Tuesday.

Sir Alec, speaking on foreign affairs in the debate on the Queen's Speech which opened the Parliamentary session was making his first appearance in the House of Commons since taking over the premiership.

The leader of the Opposition, Mr. Harol Wilson, inter-vening, asked the Prime Minister to make it clear that in Southern Rodesia there were to be protection for the rights of majorities and whether he would pledge that independence would not be granted until Southern Rodesia had a democratic constitution.

Sir Alec said he brough it had been implicit in what he had said that the Government respected the principile that the majority should rule "The very essence of a true democracy is that every minority, whether black or white, should be protected, he added.

# Ayiluka Gbo'de....

(O bẹrẹ loju ewe Karun)

## Oye Jagun

Oba Adele keji se pupọ fun ọrẹ mi Dokita E N O Shodeinde, ọga agba ile iwe ti nwọn ti nkọ awọn onișegun nșẹ, ti o dalẹla oye JAGUN EKO, șugbọn iru oye wo ni Ọba Adele fẹ fun TITI iyawo ENOS, tabi ẹ ko mọ wipe Oyinbo ko jẹ fi alarede silẹ.?

Ẹ jọwọ; ẹ ba wa wa oye Ajagun obinrin fun TITI alarede Dokita Shodẹinde nitoripe bẹ ni awa nșe ni ilu Ẹgba ti dokita na ti wa.

Mo gbọ wipe Ọba Adele na fẹ fun Alhaji Lasisi Oji'ulu ni oye Olotu Eko laipẹ yi. Ki awọn alapata ma mura ati ra așọ ẹbi silẹ loku nitoripe oye Olotu na a ka mama, ara oko a wi fun ara ile Alhaji Oloye Olotu, ẹ ku pamọ.

## Olowo Ereko

Ọrọ oye yi jẹki nnran awọn ọrẹ mẹta kan ni adugbo kan l'Ereko ni Eko ti nwọn ndu ọna barabara lati d'Olowo Ereko. Mo gbọ wipe nwọn ti lọ ya owo-ele lọdọ baba kan ni Ebute-Mẹtta; nwọn ti ra IGBA MẸTA, EIYELE MẸTA, IGAN AȘỌ FUNFUNMẸTA ORU EPO MẸTA, ekanna tọwọ ati tẹsẹ, nwọn ti ko wọn to OMISAȘEGUN lọ wipe ki o ba wọn șe awure-ẹda. Baba onișegun na si nkorin mọ agbo wọn lọwọ.

Ẹnyin ara Ereko mọ Agoro mọ Idumọta, ẹ ma wipe ẹ ko gbọ o, ija kan mbọ larin awọn ọdọmọde ti nwọn fẹ dolowo ojiji.

## Sunmbo Jibowu

O ya mi lẹnu pupọ lati gbọ iku ọrẹ mi ti a ti ma jọ nșere pọ ni ile iwe ni Abẹokuta, ọrẹ mi na ni Sunmbọ Jibowu, aburo Ologbo Olumuyiwa Jibowu, Adajọ agba.

Mo nranti ọjọ ti a ma nwa awọn ọmoge kiri ni Ake, Igbein, Iporo-Ake, Idi-Aba, Ijaiye, Owu ati Ikereku. Sunmbọ mọ ẹsẹ ja daradara, șugbọn tirẹ ko to ti ọrẹ wa Ọgbẹni Ibikunle John (D I J) ti o wa ni Ibadan nisisiyi. Ẹnikẹni ti o ba fẹ di wa lọwọ, a fi ẹsẹ gba a lehin junu; ọkan ninu awọn ọmọlehin wa ni Ladipọ Sosan, ọga awọn awọn wole-wole (Sanitary Supt) ti o wa ni Ipinlẹ Iwọ Orun nisiyi. O ko le ri Ibikunle ki o ma ri Ọlalekan; o ko le ri Ọlalekan ki o mọ ri Sunmbọ.

Ara Ijeun, ọrun re o.

## Wonpala Kan Kosi: 'Lagido' Ọyinbo Parapo Mo Sifun Re

EBUTE-METTA— Onirohin wa ni Apapa kọwe si wa wipe Oyinbo kan ti nwọn npe orukọ rẹ ni Andrew Webber, ti o nșe lẹẹ nile ișẹ ti awọn ti nta awọn apowe, ti o fẹran lati ma pe awọn enia dudu ti o wa nibi ișe awọn ọga ti o ru wa ilẹ yi ni LAGIDO—ỌBỌ—DUDU paapa ti gba iwe lọdọ awọn ọga ti o gba a sișẹ wipe o ni lati pada sile nitori ijangbọn ti o nda silẹ lemọ lemọ larin awọn enia-dudu ti o mba awọn șișẹ.

## Okunrin Kan Ku Soko Ole L'Eko

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

Nibiti nwọn gbe nwọ awọn irin na lati ji wọn ko lọ sinu ọkọ ti nwọn gbe si itọ omi, ni ọgbẹni afunnisọ ti nwọn ni ki o ma șọ awọn ọgba ni taji ti o si ntọpasẹ awọn ọlọșa na lọ.

Gẹgẹbi irohin ti a gbọ, baba afunnisọ (night watch man) na ti awọn Oyinbo bankole na gba sibẹ, tanna ọwọ rẹ. o si ri wipe awọn ẹlẹgiri lowa nibe ti nwọn nfẹ ko irin ikọle sinu ọkọ wọn.

Bi awọn ẹlẹgiri ti na rii, awọn na sare sun ọkọ wọn si iwaju, șugbọn ẹsẹ ọkan ninu wọn yẹ, o bọ somi, iyẹn na ni ọwọ rẹ, ti o ku sile iwosan l'EKO.

Ẹnikẹni ti ko ba ri ọmọ rẹ tabi burọda rẹ, ki o lọ bere awọn oku ti o wa ninu ile-yinyin ni ile iwosan Eko tabi ni Ibadan ati Enugu.

## Oko Iyawo Da?

(O bẹrẹ loju ewe kinni)

wa ninu oa, șugbọn ọgbẹni na ni on kọ. O tun șe alaye fun adajọ wipe irohin pataki ti on gbọ nipa ọmoge Sule nigbati o ba ba ọkọ ofurufu lọ si ilu Oyinbo ni ko jẹ ki on gbe larede mọ, a fi ọmoge kan ti nwọn npe ni Felicia Fọlashade ọmọ Shobande ti on șẹșẹ gbe lọșu yi ti o kọja yi ni iyawo on.


**MERCEDES — BENZ**

*Vehicles are Built to last, to give many years, and many miles of trouble-free, economical Service.*

MERCEDES-BENZ





**LEVENTIS MOTORS LTD.**

LAGOS, APAPA, IBADAN, KANO, KADUNA, JOS, PORT-HARCOURT, ABA.

*Sub-Distributors:—*

**ARMELS TRANSPORT LTD.**

BENIN-CITY . ONITSHA . ABA.


Printed and Published by The Union Printing and Publishing Company, 28, Kosọko Street, Lagos
Phone 23370; Editor; (Olotu) Ọla Ọnatade, 15, Kosọkọ Street, Lagos, Box 467